# GBO BI WON TI WI

## ỌRỌ LORI OYE ẸLẸRINMỌ
(Lati ọwọ Ọmọ Ibilẹ Ẹrinmọ)

Olotu Irawọ Obokun jọwọ mi laaye diẹ bi o ba le gba mi ye diẹ ninu iwe irohin rẹ olokiki lati ba awọn opuro ati alasọtọ Ẹrinmọ sọrọ bi melo kan.

Ọgbẹni ti o sọrọ nipa iwadi ti Ajẹlẹ ṣe ni Ẹrinmọ pẹlu Ajẹlẹ Agba ti Ọyọ, ti o jade ninu Irawọ Obokun ti September 26, ko sọ otitọ, opurọ enia ni ẹniti o ṣe irohin na.

Ni ọjọ iwadi na, Ajẹlẹ Agba ṣe iwadi finifini, lati mọ ẹniti o ni ẹtọ lati jẹ oye Ẹlẹrinmọ.

Lẹhin ti Ajẹlẹ ṣe iwadi lọtun ati losi, ti Asede Owoeyẹ sọpe Ọyọ ni wọn bi baba on, ti Job Oyeyẹmi sọpe Baba on Ọboye jẹ oye Ẹlẹrinmọ pe ori oye Ẹlẹrinmọ ni wọn bi on si, ni wọn ka awọn enia ti o wa lẹhin wọn.

Awọn ọkunrin ti o wa lẹhin Job Oyeyẹmi fi enia meje ju ti Asede Owoeyẹ. Awọn obirin ti o wa ni ẹhin Asade Owoẹyẹ ju ti Job Oyeyẹmi lọ bi enia mẹwa.

Ọpọlọpọ iwadi ni Ajẹlẹ Agba ti Ọyọ ṣe ni ọjọ na ti onirohin na ko ṣe irohin otitọ. Ajẹlẹ bere bayi lọwọ Asede pe ti Baba rẹ ba ni nkan ti idi okunrin wa, ti idi obirin si wa, pe tani o ni ẹtọ lati mu nkan Baba wọn na. Asede dahun pe idi ọkunrin ni o ni ẹtọ lati mu nkan ti Baba ba ni.

Ajẹlẹ tun ṣe iwadi, pe nipa ti oye jijẹ, ti idi ọkunrin ba wa, ti idi Obirin ba wa, tani ẹtọ fi jẹ oye ninu wọn. O tun dahun ni ọjọ na pe idi ọkunrin loni ẹtọ lati jẹ oye. Ajẹlẹ bere lọwọ ọkunrin ilu o si tun bere lọwọ obirin ilu Ẹrinmọ, wọn sọ pe idi ọkunrin loni ẹtọ lati jẹ oye.

Ajẹlẹ bere awọn to fi oloye jẹ wọn sọ fun pe ni Ẹrinmọ ni awọn ti ma njẹ oye, nwọn ni awọn ki wa si Ileṣa lati jẹ oye Ẹlẹrinmọ. Awọn ti nfi ẹni joye lo fi Job Oyeyẹmi jẹ oye gẹgẹbi aṣa Ibilẹ. Ajẹlẹ ṣe iwadi lọwọ awọn afinijoye wọn si ṣe alaye fun.

Ajẹlẹ si sọfun wọn pe ki ẹnikẹni maṣe ja, pe wọn yio gbọ irohin iyọrisi ọrọ wọn ni nipẹ.

Pataki ọrọ ti o jẹ otitọ tọ ti awa ọmọ ibilẹ Ẹrinmọ afẹ nipe, kiṣe ẹtọ pe ki a gba nkan oninkan lọwọ rẹ toripe ọmọ loninkan ko ni owo lọwọ. Ẹ gbiyanju lati gbe ijọba otitọ kalẹ o, ẹnyin oṣelu ati ijọba titun, ti a npe ni ijọba ominira.



ARABIRIN A. O. FADAHUNSI

Nibi ere ẹṣẹ kikan (Boxing) ti awọn elere ikanṣe ṣe ati fi ṣe ẹyẹ fun Ọgbẹni Y. K. M. Mackenzie ni irọlẹ ọjọ Satide to kọja. On lo pin iwe eri ti wọn fi fun awọn ọkanṣẹ to ṣe dada lọjọ na. Wọn ṣe ẹyẹ na fun Mackenzie nitoripe on yio fi ilẹ Ijẹṣa silẹ laipẹ, on si ni Baba ẹgbẹ na.



PROPHET JAMES OLA TELUDALASE

On lo ti jẹ aṣoju Irawọ Obokun ni Oṣogbo tẹlẹ ri. Lati nkan bi ọdun kan sẹhin ni a ko ti gburo rẹ mọ. Ṣugbọn on lo kọwe dupẹ lọwọ Oluwa ninu iwe wa ọsẹ yi fun idari ẹmi ti Oluwa fi mu rin irin ajo iwasun ihinrere. Woli na ti pada de si 156 Station Road, Oṣogbo.

## ESI SI ỌRỌ ỌGBẸNI AYILUKA
(Lati Ọwọ Ajibike)

Olotu Irawọ Obokun ati ẹnyin ọkawe Irawọ Obokun, gbogbo yin ni mo ki ki nto bere ibere ọrọ mi lọwọ Ayiluka.

Njẹ Ọgbẹni Ayiluka le ṣe alaye ati idirẹ ti o fi sọ wipe Ọga onifoto ulu jibiti ijọjọ ati ẹṣẹ kikan pelu idahun si awọn ibere wọnyi?

Njẹ o ṣe akiyesi bi awọn elere ti a fi iwe akiyesi sode fun wa tabi wọn ko wa gẹgẹbi a ti ṣe iṣẹ ninu iwe akiyesi na?

Njẹ o le sọ iye awọn enia ti awọn elere iṣere na gbowo agbalagba lọwọ wọn ti wọn ko si bi anfani lati woran tabi jo ijo na.

Njẹ o le sọ awọn enia, ati oruko wọn, ti wọn gba iwe iworan ni ọjọ na ṣugbọn ti awọn elere ere na ko jeki wọn wọle.

Njẹ o le sọ iwe owo ti wọn ya lọwọ Ayiluka; Nigbati wọn le sọpe tọju iwe eri re lọwọ di ọjọ ayan?

Ki o tun dahun awọn ibere wọn yi lori jibiti ẹṣẹ-kikan.

Njẹ o le sọ iye owo ti wọn na ki o to di wipe wọn le ṣe ere Eṣẹ kikan na.

(2) Njẹ o le sọ Adehun ti o wa larin awọn elẹṣẹ ti Ifẹ ati ti Eko pelu awọn to pe wọn. (3) Elo ni [illegible] wọnyenna, elo ni ere.

(4) Njẹ o gba aṣẹ lati ọdọ Baba elere ikanṣẹ ki o to di wipe o sọ itu ọrọ yi si inu iwe fun gbogbo awọn ọkawe Irawọ Obokun.?

Ti awọn ibere wọnyi ba wuwo fun Ayiluka lati fesi, mo pa lasẹ fun lati sọrọ aforiji lati ọwọ [illegible] Ọga Onifọto Akinọla ọmọ Odeyẹmi Ajikẹbi. Ki o si tuba gbogbo ọrọ ti o sọ pada sinu Irawọ Obokun pe irọ ni ati papa ki o tọrọ aforiji lọwọ Ọga Onifoto.

## IRAWO OBOKUN FUN ERINMO

Enikẹni ti o ba fẹ lati ra Irawọ Obokun ni Ẹrinmọ ati agbegbe rẹ ki o bere lọdọ Ọgbẹni Samuel O. Ogunuele, Ọna Ẹffọn No 644 Ẹrinmọ.

## FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKO

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ N.C.N.C mọ pe ipade ọjọ mẹjọ-mẹjọ ti a nṣe ni Wednesday ko yi pada; nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.

# E MA RA IRAWO OBOKUN KA

## OBIRIN NWOṢỌ ONIHOHO KIRI

(Lati Ọwọ Ade's Adeyọkunnu O 135 Ikoti)

Kini idi rẹ ti a fi bi ọmọ ti a ko le bawi?

O yami lẹnu fun awọn obirin Ilesa ti nwọn nwọ aṣọ onihoho kiri, ọpọlọpọ ọmọbirin lo wa ti wọn loyun lai lọkọ. o dun mi fun iru awọn enia bẹ, atipe ki wọn ba wa kilọ fun wọn, ki wọn ma jo ijo "Kusi wọn laya" ti nwọn njo kakiri mọ. Ijo ẹpe ni o.

Mo bẹ Olotu Irawọ Obokun lati gbami laye nipa ọrọ yio, Obokun ko ni jẹki enia kusi mi laya ni temi o, Amin o. Ibi ere iparuku ni a ti ma nmọ Ọmọ ti o ba ma nilari.

Nwọn ngbe ara wọn ṣepe, wọn a ma ro aṣọ bi elegbo. Aṣọ wọn ko ka wọn, wọn a si toromọ leri ko ma ba gbe wọn lulẹ.

Akoko "Kusi wọn laya" ni wọn ngba oyun lailọkọ rara.

Ẹ jọwọ, ẹ gbọ na, nigbati wọn ba ro aṣọ wọn bi ti elegbo yi tan, ti wọn ba wọ ẹwu onihoho wọn yi tun pelu awọtẹlẹ pupa pẹlu akun pupa lọwọ, wọn a si ma rin gẹgẹ bi akan, wọn a wọdi si apakan bi adiẹ ti ẹyin fọ mọ ninu.

Awọn ti wọn ko mọ iwe rara lo nkọ aṣa na, ti wọn gbọ ede Oyinbo agbọsori. Ti o ba bere iṣẹ ti wọn nse, wọn a si dahun pe "I am a Sewing" "Ayamu ẹsoyin". ti ijo Kusi wọn laya ko jẹki wọn o fi oju si iṣẹ mọ. Wọn ngẹ ori wọn bi opo ti ọkọ rẹ ku, ti o ba di igba miran ma juwe ọpọlọpọ fun nyin.

## KINI ITUMỌ KẸRẸMUDU ?

Lati ọwọ Moses F. Ajiwẹ, N.A School Ikirun.

Olotu, jọwọ gba mi laye diẹ ninu iwe ti irohin ọsọsẹ lati bere itumo ọrọ yi ti wọn npe ni KẸRẸMUDU."

Orukọ yi jẹ ẹsiti awọn ọmọ Ijẹṣa to wa ni ilu Ikirun, ati agbegbe rẹ, to nse ipade ọṣọṣu mẹta npe ẹgbẹ wọn. Kiki ọmọ ibilẹ Ijẹṣa lo wa ninu ẹgbẹ na.

Nigbati mo kọ gbọ orukọ yi o ya mi lẹnu nitoripe nko mọ itumọ rẹ. beni wọn ko si pa ni itan fun mi ri pe orukọ miran ti a le pe Ijẹṣa ni KẸRẸMUDU

Mo sun mọ awọn ọrẹ mi to jẹ Ijẹṣa bi temi lati bere itumọ orukọ yi, ṣugbọn alaye wọn ko bojumu nitoripe seni itumọ na ba ẹgbẹ daradara na lorukọ jẹ.

Itumọ ti wọn fi han mi wipe, nigbati wọn kọ da ẹgbẹ na silẹ wọn a ma mu ẹmu pẹlu ifẹ nla

kan 'Kẹrẹdu' eyi lo wa mu wọn kuku sọ orukọ ẹgbẹ na ni 'KẸRẸMUDU'.

Awọn a gba ama pa lowe pe bile ba tiri ni a nwo sọmọ lorukọ. Eyi wa han gbangba nipa iru ilẹ ipade bayi, nitoripe bi ọmọ Ijẹṣa ti pọtọ ni agbegbe yi, o fẹrẹ jẹ pe ẹmu ati iyan ni wọn npe jẹ ni ọṣọṣu mẹta mẹta na, a pe ko si ọrọ iyanju kan tabi ti anfani kan pataki ti ẹgbẹ yi nsọ iti wọn yio fi tuka.

Mo fẹ ki ọga ẹgbẹ na dahun ohun rere ti wọn ti ṣe, tabi ti wọn ngbero lati dowọ le fun ire ati idagba-soke ilẹ Ijẹṣa.

Orukọ rere san ju wura ati fadaka lọ nitorina kiẹ gba ọrọ yi yẹwo, ki ẹ ma si fi ṣe tija'

Obokun a mẹsọ gbogbo wa dele layọ o.



ỌGBẸNI OLUFẸMI OWOẸYẸ

On lo sọ itan awọn ọmọ baba mẹta, ti ọkan ni ikoko taba ti ekeji ni taba ti ẹkẹta si ni ina. Awọn mẹtẹta ni lati da awọn ohun ini wọn jọ wọn to le mu ikoko. Ajoku iru ikoko d'obirin, ẹnikọkan ninu awọn mẹtẹta si fẹ fẹ obirin na Ọgbẹni yi wa nbere pe tani ọmọbirin na tọ si.

## A JỌDUN KAFINTA NI IPARI OṢU YI.

Lati ọpọlọpọ ọjọ sẹhin ni awọn ẹgbẹ Kafinta Capenters' Union) ti ilẹ Ijẹṣa ti nsẹ imurasilẹ fun ipade ajọdun wọn, eyi ti wọn fẹ ṣe ni Ilesa lọdun yi.

Ni ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni ipade Ajọdun na yio bẹrẹ, a si gbọ pe wọn yio pari ipade na ni ọjọ kọkanlegbọn oṣu yi.

Ọgbẹni G. O. Ikọtun, ẹniti o jẹ akọwe ẹgbẹ na sọ fun wa pe aṣoju awọn ẹgbẹ Kafinta yio wa si ipade na lati ilu Amerika, Belgiun, Capenhagen ati ni ọpọlọpọ ilu Gẹsi, Gold Coast ati ọpọlọpọ ilu enia dudu.

O si tun fi ye wa pe ọkan ninu awọn Minista ti ijọba Ẹkun Iwọ Orun Naijiria ni yio wa si ipade na. O si tun fi yeni pe ọpọlọpọ awọn pataki pataki pẹlu Alayeluwa, Ọwa Ajimọkọ keji ni wọn yio pe lati wa si ipade lọjọ ti wọn yio si ipade na.



AWORAN AWỌN ỌMỌ ẸGBẸ IRANLỌWỌ GBAJUMỌ

Eyi ni aworan awọn ọmọ ẹgbẹ Iranlowọ Gbajumọ. Ẹgbẹ awọn Gbajumọ na ni Ọgbẹni Joseph Ajayi Teniọla to di Ologbe jẹ Olori rẹ. Ẹgbẹ najẹ ọkan ninu awọn Ẹgbẹ Gbajumọ ni ilẹ Ijẹṣa. Ogunlọgọ awọn ọmọ Ẹgbẹ pataki pataki miran lo tẹle oku Ologbe na de iboji rẹ. Diẹ ninu awọn Ẹgbẹ to lo sibẹ ni Ẹgbẹ Ijẹṣa Ọrẹdẹgbẹ Society, Ẹgbẹ Ifẹlodun

# IROHIN LATI AGBEGBE

IKEJI TITUN

## IKOMỌ AYỌDELE MINRINGINDIN

Ọgbẹni T. O Ayọdele, ọga Ile Ẹkọ Peteru Mimọ 'B' nibi pẹlu iyawo rẹ ṣe ikomọ ni ọjọ isimi ti ọjọ keji oṣu yi.

Lati Satide ni awọn olukọ ati ọmọwe gbogbo ti afi ijo p'ẹta ni ile awọn obi ọmọ titun na. Awọn onilu ọjọ na si Ikeji High Life Orchestra labẹ ọgagun Ọgbẹni E. Ilesanmi Ojo. Nwọn ṣere titi di nkan bi agogo mejila ki olukuluku to lọ sun ni alaja lojọ na.

Lati afẹmojumọ titi ile fi ṣu ni ọjọ ikomọ yi ni ọpọ ninu awọn ara ilu ati awọn ti o ti idale wa nje ti wọn si umu. Ni ile Ọlọrun Peteru Mimọ ni ọpọlọpọ ẹbi ati ọrẹ ninu aṣọ ẹgbẹjọda wọn tẹle awọn obi ọmọ na lọ dupẹ lọwọ Ọlọrun ti Alufa D. O Ladimeji si fi IBIYẸMI OLUBUKỌKA sami fun ọmọ titun na.

Ni gẹrẹ ti nwọn jade ọsẹ ni gbogbo awọn ti o wa se ẹyẹ ti ọmọ na ya aworan ni ile awọn obi ọmọ na, ti awọn ọmọwe gbogbo si pejọ si ibi ase nla ti wọn ṣe fun wọn.

Ẹnitì o ṣe alaga ibi ase nla yi ni Ọgbẹni I. A. Oni, Ọga Ile Ẹkọ ti Paulu Mimọ 'B' ni Ipetu Ijẹṣa. Ọgbẹni J. S. O Fapojuwo sọrọ iwuri pupọ nipa awọn obi ọmọ na. Ọgbẹni J. O Ayọdele, baba ọmọ na si fesi pẹlu idupẹ lọwọ gbogbo awọn ti o wa ṣe aṣeyọ na. Ọgbẹni G. A Olugemọ ati Omidan P. O Awopetu ni o ṣe iwọle (M. C) nibi ase nla yi, awọn ti o si joko jẹun ti nwọn si mu nibẹ pọ pupọ.

Diẹ ninu awọn ti o wa sibi ikomọ na ni awọn Iya-afin Comfort Ọlunla Ayọdele (Iya baba ọmọ na) ati A. M Ladimeji, Okubanjo, Ayọ Fowowe, Ojẹniyi, E. A. Ọderinde, J. S. O Fapojuwo ati iyawo rẹ, R. O. Ajayi, R. O Ọlọjọ, I. R Bankọle, H. O Agbọla J. O Bankọle, Fatoki, Kẹhinde Ọdanye Fẹmi Ayọdele, Ajewọle, Jimọ, Omidan E. O Ijaduọla, J. A Babadiya, D. O Apata, D. B Ẹladiya, P. O Awopetu, L. M Adetuberu, D. O Adetuberu, J. F Sunmibọla pẹlu ọpọlọpọ ọrẹ ati ẹbi lati Erin Odo, Ipetu Ijẹṣa, Ileṣa ati Oṣogbo.

## ISAMI ỌMỌ ADE AGBO AKILO MINRINGINDIN

Nigbati o ti ku bi ọsẹ meji ti October 2 yio de, ni Ọgbẹni Ade Agbo Akilo fi iwe ipeni sibi ẹyẹ isami ati ipanu tẹ awọn ọrẹ, ibatan ojulumọ, ẹgbẹ ati ọgba lọwọ.

Wọn ṣe aisun ọjọ ayọ na ni alẹ ọjọ kini mọju ọjọ keji oṣu yi. Lati owurọ kutu ọjọ isami na ni awọn ti iwe ipe tẹ lọwọ ti nde pẹlu awọn ọrẹ wọn.

Ọpọ eniyan lo ti Oṣogbo, Iwara Oṣu ati Ibominran pẹlu ti Igboro Ileṣa, wa si ibi ẹyẹ na. Gbogbo wọn lo tẹle iya ati baba ọmọ wọ aṣọ ọlọwo iyebiye lọ si ile Ọlọrun ti Ijọ Mẹtalọkan ni Oke-Ọmọfẹ. Gbogbo wọn ni ṣe idupẹ.

Lẹhin isin ni Ẹni Ọwọ J. O. Daramọla ṣe isin isami fun ọmọ na. Ọgbẹni James Egundebi, ti o ṣe baba isami ati Arabirin J. A Daramọla ti o se iya isami ọmọ na fun ni orukọ isami yi, "Ṣonibarẹ Adewale" Lẹhin isami na ni wọn ya aworan pẹlu gbogbo awọn ti o ba wọn wa ṣe isin na.

Lẹhin isin ni ogunlọgọ enia lo si ile baba ọmọ ni Ikoti. Ọgbẹni S. A Adegbayibi lo ṣe alaga nibẹ. Wọn ti ọpọlọpọ ohun jijẹ ati mimu tẹ wọn lọrun nibẹ.

Diẹ ninu awọn to wa si ibi aṣeyẹ na ni awọn Ọgbẹni Fayoṣe, J. A. Fawẹkun, Layọkun, Yẹye, Akinọla, Owoeni, Olatuyi, Adeyẹmi, Fadahunsi, Ndukwe, Bankọle, Olowe, Aluko, Adenigbagbe, Ileṣanmi, Sem. Anla, D. A Apata. Awọn arabirin Ọgẹ Apata, Yẹmisi Fakorede, Fọlakẹ, Fakorede, Olu; Makinde, Bọla Fawẹkun, Omidan Ajinawo Adejugbagbe, E. Jegede, Apoeiọ, Obembe ati ọpọlọpọ enia.

## ARA OKE-IGBO DA IPADE SILẸ

(Lati Ọwọ Ọgbẹni Simoni Olubọde Ọlatunbosun)

"Isa mi yio dun bi Olọtu Irawọ Obokun ba le gba aili aye lati sọrọ le lori ẹgbẹ awọn ọmọ Oke-Igbo.

Awa Ẹgbẹ Ọmọ Oke-Igbo ti ọna Iwara da ipade pataki silẹ fun anfani ilu wa ni ile Baba wa Tẹmọla F 13 Eregenu St. Ileṣa.

Awa Ọmọ Ẹgbẹ yi ni Irẹpọ ati ifẹ lati ran ara wa lọwọ, lati ran awọn ara wa tiko ba riṣẹ tabi ti o, wa ninu aisan lọwọ, atẹyiti o julọ lati gbe ogo ilu wa ga.

Ifẹ yi pọ pupọ tobẹ ti awọn ara wa ti o wa ni Omi-Adio fi ran Ọgbẹni Abraham Ademorọti lati wa wo wa ati lati sọrọ iwuri nipa irẹpọ fun wa. Ọgbẹni na si sọ ọrọ lori Ifẹ. Ipade na lariuru pupọ ni ọjọ karundogbọn oṣu to ikọja ni a ṣe ipade na ni agogo kan ọsan.

Iwe mimọ Bibeli sọ funni pe 'Ẹgbẹ ni fun ẹnití o fi ọwọ osi juwe ile Baba rẹ" Ṣugbọn awa dupẹ pe ti wa ko ribẹ.

Ẹ jọwọ gbogbo ẹnyin ti ẹ ba ti agbegbe wa si Igboro Ileṣa o yẹki iru ifẹ yi le gbera lọkan ẹni kọkan lati ni irẹpọ pẹlu agbegbe ti olukoluku ti wa ati pẹlu lati wa ire ilu wa. Obokun A gbe wa o.

ILOKO

## JOEL FADARE JẸ ỌDỌFIN ILOKO

Ni ọjọ karundogbọn oṣu to koja ni wọn fi Ọgbẹni Joel Fadare jẹ Ọdọfin Iloko. Ni ọjọ kẹta oṣu yi ni oloye na ṣe ijẹ oye rẹ.

Lati owurọ ọjọ na ni ọpọlọpọ ero ti nwa lati awọn ilu agbegbe lati ba oloye na ṣe aṣeyẹ oye rẹ: Oloye na ati awọn ọrẹ, ibatan ati ojulumọ rẹ ṣe inawo tobẹ to fi jẹ pe gbogbo awọn ero to lọ si bẹ lo jẹ ajẹtẹrun ti wọn si mu amutẹrun.

Oye marun ni wọn jẹ lọjọ ti wọn jẹ oye Ọdọfin na. Gbogbo awọn oloye na lo ṣe inawo lọjọ ijẹ oye wọn.



ARABIRIN AJAYI

Ninu iwe wa ọsẹ yi, akọwe awọn akẹkọ ọmọ Ijẹṣa to wa ni Oyinbo sọ ninu iwe to kọ si wa pe kosi awọn ọmọbirin ninu awọn akẹkọ ni ilu oyinbo. Ṣugbọn gẹgẹbi a ti mọ nipe Arabirin wa yi jẹ ọkan ninu awọn ọmọbirin Ijẹṣa to nkẹkọ lọhun. Bi akọwe na ba sọpe wọn ko pọ to a le fara mọ.

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

| | | | |
|---|---|---|---|
| **OJU EWE KINI** | | | |
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |
| **OJU EWE KEJI** | | | |
| Igba | 1—12 | 5s | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |
| **OJU EWE KẸTA** | | | |
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. " | " " " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |
| **OJU EWE KẸJỌ** | | | |
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

